**BALEWA SO PE :**

# OFIN PAJAWIRI KO W'AIYE NI IPINLẸ IWỌ ORUN

IBADAN:- Ninu ọrọ to jade lẹnu Alakoso apapọ Ijọba Naijiria Alhaji Balewa nigbati awọn akẹkọ ile ẹkọ giga Unifasiti ti Ibadan ti nba nsọrọ lori rogoodiyan to nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati pe ki o ṣe eto ofin pajawiri si Ipinlẹ na ni o ti ṣe alaye pe eto ofin pajawiri ko waiye ni ipinlẹ na lori rogbodiyan to nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na.

Alhaji Abubakar tun ṣe alaye pe ko si ohunti ole fa ti on fi ṣe eto lati gbe ofin pajawiri de Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lori rog odiyan to nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na lori abayọri idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to kọja lọ yi.

Alhaji Abubakar ti iṣe Alakoso ile ẹkọ giga julọ ti Unifasiti ilu Ibadan ba awọn Igbimọ Akẹkọ ile ẹkọ na nsọrọ ni alẹ Ọjọ iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun Oṣu yi.

Alhaji Abubakar tun ṣe alaye fun awọn Akẹkọ ile ẹkọ giga na pe ki iṣe wipe nwọn kan nṣe eto ofin pajawiri si Ipinlẹ kan ni orilẹ ede Naijiria laijẹ wipe apapọ Ijọba si tẹle eto Ofin ki nwọn to le ṣe eto lori ọna bi nwọn ṣe le ṣe eto ofin pajawiri si Ipinlẹ kan ni ilẹ Naijiria.

EDEAIYEDE

Alhaji Abubakar tun ṣe alaye pe to ba tilẹ jẹ wipe awọn enia Ipinlẹ kan npa ara nwọn ti ko ba ti se pe awọn Alakoso Ijọba meji lo wa ni Ipinlẹ na lati ma ṣe eto akoso Ijọba ni Ipinlẹ na o ni eleyi lo le mu ki apapọ Ijọba ṣe eto ofin pajawiri si Ipinlẹ ti iru nkan bayi ba ti ṣelẹ.

Siwaju si i Alhaji Abubakar tun ṣe alaye fun awọn Akẹkọ ile ẹkọ giga ti Unifasiti Ibadan na pe ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria bayi si jẹ edeaiyede larin awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu.

Alakoso apapọ Ijọba Naijiria tun ṣe alaye pe gbogbo Ijọba Ipinlẹ Naijiria lo ni eto ofin tirẹ ati pe ko si ohunti o le mu apapọ Ijọba Naijiria lo dahun si ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ kan laijẹ pe ko si eto ofin tabi Ijọba rere to fi idi mulẹ ni Ipinlẹ na lo jẹki apapọ Ijọba Naijira dahun si iru ohun ti o ba nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na.

Ọkan ninu awọn Akẹkọ ile ẹkọ giga na bere lọwọ Alakoso apapọ Ijọba pe kini ṣe ti apapọ Ijọba ṣe



**Alhaji Abubakar Tafawa Balewa**
Alakoso Ijọba Ilẹ Naijiria

Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni ninu ọdun 1962 ati pe kini ṣe ti apapọ Ijọba Naijiria ko ṣe eto ofin pajawiri si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nigbati nwọn mọ nipa ọna eru ati jibiti ti nwon fi ṣeto ibo ti awọn enia Ipinlẹ na di ninu oṣu to kọja lọ yi ati pe ti ọpọlọpọ enia si ti padanu emi wọn.

Alhaji Abubakar tun da awọn Akẹkọ na lohun pe ohunti o ṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ninu ọdun 1962 si yato si ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nisisiyi eyiti o jẹ wipe rogbodiyan na si jẹ nipa ti eto ọrọ iṣelu.

O tun ṣe alaye pe lori ohunti o ṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ninu ọdun 1962 si jẹ rogbodiyan lori Alakoso Ijọba meji ati Gomina meji ni Ipinlẹ na ni asiko na eyiti o mu ki Apapọ Ijọba ṣe eto ofin pajawiri si ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ninu ọdun 1962.

Alakoso apapọ Ijọba tun ṣe alaye pe lori ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni o ti ṣe alaye pe Ijọba ti o wa lori eto ofin si wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria o ni otitọ ni edeaiyede le wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu.

Nigbati awon Akẹkọ ile ẹkọ giga na tun bere nipa awọn aiṣe dede tabi alebu to wa ninu eto abayọri idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Alhaji Abubabar Tafawa Balewa tun da awọn Akẹkọ ile ẹkọ giga na lohun pe on ko mọ nkankan nipa eto ibo ati pe on ko si nse eto nipa ibo didi pe ki on mọ nipa alebu tabi aṣe dede to wa ninu eto ibo ti nwọn ṣe ni Ipinlẹ na.

Alhaji Balewa tun ṣe alaye fun awọn akẹkọ ile ẹkọ giga na pe ti madaru ba wa ninu eto ibo ti nwọn di si ile Igbimọ aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, o ni eleyi ki iṣe ohunti o le pupọ bikoṣe pe ile ẹjọ si wa lati gbọ ẹjọ aiṣe dede to wa ninu abayọri ibo lọ, eyiti wọn yio ṣe lori eto ofin.

Alakoso apapọ Ijọba Naijiria tun pe akiyesi awọn akẹkọ ile ẹkọ giga na si iru awọn iṣẹ ribiribi ti on ṣe lori eto idibo si ile Igbimọ aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun to kọja lọ yi.

O ni on awọn fun Ọlọpa ati Ṣọja ni aṣẹ lati ba awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti wọn ylo dibo fun lọ si ile iṣẹ akọwe eto ibo lati da abo bo wọn ki nwọn si le fi iwe aṣẹ ti nwọn yio fi fi orukọ wọn silẹ.

Alhaji Abubakar tun ṣe alaye pe eleyi si jẹ ohun to ṣe pataki julọ ti o jẹ pe ole mu ki eto idibo si ile Igbimọ aṣofin Ijọba Ipinlẹ na lọ ni ọna eto ofin ti ki yio si madaru.

O tun ṣe alaye pe on se eto ti ki yio fi si ija tabi rogbodiyan lasiko idibo si ile Igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ninu ọdun to kọja eyiti edeaiyede fẹ bẹ silẹ lasiko na.

Alakoso apapọ Ijọba tun ṣe alaye pe ti ko ba jẹ pe iru eto ti on se laisiko na, o ni ọpọlọpọ ko ba padanu emi wọn lasiko idibo si ile Igbimọ Aṣofin apapọ Ijọba Naijira eyiti laijẹ silẹ ki ba fi ṣẹ'e ni asiko na.

Alhaji Balewa tun ṣe alaye pe ko sibi rogbodiyan le to ni Ipinlẹ kan eyiti ojẹ pe Ijọba to wa ni Ipinlẹ na si wa lori eto efin ati pe ko si ohunti o le fa ti Apapọ Ijọba ko ni wa lẹhin iru Ijọba bẹ.

Nigbati awọn ọmọ Akẹkọ na tun bere lọwọ Alako

WO OJU EWE KARUN

# Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

## Ijoba UPGA Ni a nduro de

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to nta bi akara gbigbona lati kesi awọn Alakoso ilẹ Naijiria ati paapa julọ apapọ Ijoba ilẹ Naijiria lati tete mu oju to ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun bayi ati pe gbogbo awa enia Ipinlẹ na lo mọ daju pe ẹgbẹ UPGA lo wọle ibo to koja

Ohunti o tun ya wa lenu ni pe ko si ẹniti o dibo fun ẹgbẹ Dẹmọ ninu idibo na sugbọn a komọ ọna ti nwon gba so wipe awon lo wole ibo na

Ohunti gbogbo orilẹ ede agbaiye le jẹri si ni pe ẹgbẹ UPGA lo wọle ati pe ohunti o han gbangba tun ni pe opolopo apoti ibo eyiti ẹgbẹ Dẹmọ fi ọna eru ko iwe ibo sinu rẹ ni awọn Ọlọpa ri gbe jade ninu ile awọn olori ẹgbẹ Dẹmọ eyiti o ti ṣe apejuwe fun awa enia ilẹ Naijiria ati pe itiju ni eleyi tun je fun orilẹ ede Naijiria ni ilu okere nitori eyi Ijoba UPGA ni awa nduro de lati jẹki o ṣe ukoso wa

ninu iwe Irohin Imọlẹ to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati lo ipo wọn rere ki nwọn ba awa enia ilu Akurẹ tun ilu wa ṣe ati awọn ilu to wa ni agbegbe rẹ eyiti o je ohun ti o tọ ti o si yẹ lati se fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Gbogbo oju ọna to wa ni arin ilu Akurẹ ni ko dara ti gbogbo rẹ si ti jin koto ati pe ti ko si ọda ni oju ọna miran ni ilu na.

Mo ro pe iru nkan to nṣẹlẹ si ilu Akurẹ lasiko ti a wa yi tabi lati ọdun keta si asiko yi ko tii ṣẹlẹ ri.

Inu awa enia ilu na yio dun bi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ba le tete mu oju to eyi ati pe ki nwon si tete ṣe awon ohunti o tọ lati ṣe fun wa nitoripe a ki i fi owo ori wa jafara

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ajinde yio ma jẹ fun nyin o

Emi ni
John Adebisi
Akurẹ

Emi ni
Bunmi Adeọla
ILESHA

## Eko Fa Ọmọ Yo

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin ti nta bi akara lati fi ẹdun ọkan mi han awọn enia ti o dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre pẹlu Alakukọ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi.

Ko si ẹniti yio gbọ abayọri ibo na ti inu rẹ ko ni dun de ọkan nitoripe gbara ti ẹgbẹ Dẹmọ ti yọwọ yọsẹ lati jẹki awọn enia Eko dibo fun awọn ni nwọn ti tun ṣọ pe awọn ni ọgbọn miran ti awọn yio fi wọle sinu Igbimọ Ijọba Ibilẹ bi Eko awọn ba fẹ ki nwọn dibo fun awọn

Logan ni gbogbo wa ti mo wipe awon ti o fi ẹru nyu kuro ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nwon npe arawọn ni "omo ẹgbẹ Afẹnifẹre to da duro" ni awon ẹgbẹ Dẹmọ fẹ lo gegebi ohun elo.

Gbogbo wa ni a dupẹ pupọ ti okankan ninu won ko si wole rara ti awon ti o padanu owo idogo nwon ko ṣe fi ẹnu sọ ti nwonsi nkan abuku nigbagbogbo

Mo tun ki gbogbo ẹnyin ti ẹ dibo fun ẹgbẹ Itẹsiwaju pe lagbara Ọlọrun iwa ju ni gbogbo nyin yio ma lọ. Mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi O'otu

Emi ni
Lasisi Arẹmu
EKO

## Egbe alakuko se a sesa

Olotu jowo ran mi lọwọ ki ikọ ọrọ mi yi sinu iwe rẹ ti o ukọ wa ni ọgbọn ati oye nito ri iwe na jẹ afọna idẹra han gbogbo awọn enia tio nka lojo mejeji ko jẹ fi igbo kan bọ ọkan ninu

Bi enia bajẹ eniti nkan diẹ koto airi ara ni yio gbẹhin rẹ kosi ẹniti ko gbo wipe awon ẹbẹ Afẹnifẹre so fun ọrẹ nwọn ngbẹ Alakoso pe ki nwon fi owo wu aye yoko mẹdogun ti nwo n i ninu ile igbimo ijoba ibile Ek ti nwon ni rara o afi ki awon pin ni dede

Ki awon ota ko maa bayo ẹ gbẹ Itesiwaju nwon tun fun ore ẹgbẹ Alakukọ ni aye meji si ki gbogbo rẹ je aye metadilogun egbe Alakuko tun ta wonle bi ko oke aiya nwon ni afori awon yio pin ni bakanna

Ni egbẹ Afẹnifẹre ba kọ fun wọ it olukuluku si fi ọmọ ẹgbẹ rẹ han lati dibo fun gbara ti agbọ abayori ibo na ati mẹdẹgun ni awọn ko ri ọkan kan mu ni iu rẹ Irun Ẹlẹda wa kọ enia ki o ma ṣe ṣesa

E ku iṣẹ olotu

Emi ni
Yekini Adewa'e
Mushin

## Akurẹ nfẹ atunṣe Ijoba

Olotu jọwọ jẹ ki mi o aye diẹ

## APIAS RHUMATIC & DRAGES

Jẹ ojulowo kan ninu nbanun egbogi Jamani to lagbara gidi gidi fun iwosan "LAKUREGBE" to mba enia ja

Orişirişi lakuregbe ni o wa lakuregbe Arungun ti o ma asan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o ma nwu enia ni ẹsẹ roboto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o agbẹ orikerike danwo kori bi o ti rorun lati lo tabi ki o ma ṣe ayipada ẹsẹ, ara tita bi eyiti enia fi ata obẹ pa ibadi abi egusi ara wiwo, ako iba abi pipon tabi rirun.



Bi enia ko ba gbajumọ lati doju rẹ lasiko o le so owo pa enia

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

## Ha! Kini Eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three elephant Brand mosquito coils dara pupọ, A ri o dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa yan ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three elephant Brand coils tire loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi yio ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki ori daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu fun ọ

Three elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi.

DISTRIBUTORS

Amos GBENLE & BROTHERS
34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

# ENIA MEJI TUN KU NI IJẸBU

IJẸBU-ODE:- Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa lati Ijẹbu Ode ni kutukutu owurọ ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹtadilogun oṣu yi ni a ti gbọ wipe enia meji ni o ti padanu ẹmi wọn ni agbegbe Ijẹbu lori rogbodiyan to nṣẹ n pa eto ldibo si Ile Igbimọ Asofin Ijẹba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to kọja lọ yi.

Oniwe irohin fi ye wa pe irohin to kọ de ọwọ ọn ni ilu Ijẹbu Ode ni ti ọga ile ẹkọ ti Moslem School Agọ Iwoye Ijẹbu Ijẹbu Ode Ọgbẹni Mobiyi Oshinowo

Irohin ẹkeji ti o tun ṣe alaye ni irohin rẹ ni ti Obi kan Iyaafin Adenaike Taiwo eyiti irohin fi ye wa pe nṣe ni awọn ṣa Obinrin na pa ni ilu kan ti a npe ni Odoraṣinyin ni ẹba Ijẹbu Ode

Irohin tun fi ye wa pe awọn Ọlọpa ti ilu Ijẹbu Ode ko ti sọ ọrọ kankan lori awọn enia meji ti wọn pa irohin na tun fi ye wa pe ko ti si irohin kankan to jade lati ọwọ awọn Ọlọpa na lori ohunti o ṣẹlẹ ni ẹkun Ijẹbu na.

Irohin na tun fi ye wa pe Ọgbẹni Oshinowo si wa ninu ile ẹkọ rẹ nigbati enia na si yin ibọn si eyiti nwon tete yara gbe e lo si ile Iwosan ti Ijẹbu Ode eti pe ko pe na lo si ku.

Ninu oro Ọgbẹni Stephen Taiwo ti iṣe ọkọ Iyaafin Adenaike Taiwo ti ilu Odoraṣinyin fi ye oniwe irohin wa pe iyawo on lo si oko kan ti ko jina si ilu won lati lo ṣe igi pẹlu obinrin miran elegbere eyi ti o je wipe ninu Oko ti nwon wa na ni awon enia kan lo ka nwon mo ti won si ṣa iyawo on gegbi eni pe eran ileya.

Oniwe irohin wa fi yewa pe awon Ọlopa ti mu okunrin kan eyiti nwon ko so oruko re lori iku Iyaafin Adenaike Taiwo. Bi nwon ba ti nṣe eto iwadi awo eniti o pa awon enia meji ni si e o ma ri ka ninu iwe irohin wa.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Mase fi aye silẹ fun are oni sugbọn bi o ba ri wipe are na wọra, ki o ṣere pa ki o sun fi ara lelẹ

PISCES (Feb 21 Mar 20) Ire owo, ko jinna si ọ loni sugbọn ki o jẹki ẹnu rẹ ma bo, ko nṣe gbogbo ọrọ ni enia nsọ jade ki o ma ba sọ syiti yio yẹ ọ lẹnu

ARIES (Mar 21 April 20) Toju iṣẹ rẹ loni ki o si mogirisi, ki o si mura lati gba alejo ti o mbọ wa ba ọ.

TAURUS (April 21 May 20) Erepa kan ti o ba ọmọ biirin kan se ti di otito ki o si toju asọ rẹ lati gba iyawo titun nse ni ki o dupẹ lọwọ ẹniti o lọ ba sọ ọrọ

GEMINI (May 21 June 21) Ṣe ẹjẹ loni, mase gbidanwo lati wa ayipada nse n ki o se suru Pẹlu ohun ti o wa lọwọ ni sise

CANCER (June 22 July 22) Ọjọ oni lo dasa lati fi yanju awọn isoro ti o wa fun ọ mase tun fi digba miran mọ mase bẹru wi o tun le da ija silẹ mọ

LEO (July 24 Aug 22) Ọjọ alayọ ni ọjọ oni nitori pe nibe ni awọn enia pataki yio ba ọ damọran iwọ yio sigbọ irohin ni dun kan

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Gegebi ọgenẹti ọjo oni ti yi are tekere on yio mu o ki o si ranti pe loni o ni lati se nkan pataki kan, sugbon alafia ni fun o

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Ori rẹ si ngbona nitoripe ohun kan wa ti o jẹ isoro fun o lati yanju sugbon nwọn o mu o ni tulasi lati yanju awon isoro na

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Ire jaburata wa fun ọ loni beni iwo yio ma ni ilọsiwaju si

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Toju ara rẹ ni tori ara rẹ nfẹ alafia ati itoju o si tun fẹ isinmi daradara

CAPRICORN Dec 22 - Jan 21 Iwọ yio lori ire gba loni ohun gbogbo ti o ba si dawọle lo si yio ṣore


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI AYỌ NIPA DYNAMIREN TONIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Tọnigi amọnu tilun ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, iabi ki o male sun dada de ọkan lọsan tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ẹefun daradara ti Emi Breath inu ko ba unlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi jube lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di tun pafapata inu rẹ a jọlọ ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi yabo dada Ara rẹ yio gbe kankan ni gbakugba yio sa lo pẹlu ala fia duro de o iyẹn da Bere Egbogi ni Ṣọbu—



WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Phone 22787
LAGOS


## Atoto ! Arere !!

Eyi ni lati kede fun gbogbo enia gbọ pe, awọn ọmọ 'ẸGBẸ IJINLẸ YORUBA' yio ṣe ipade wọn ninu ile ẹkọ giga 'GASKIYA COLLEGE' Herber Macaulay Street Yaba ni deede agogo marun irọlẹ ọjọ ọjọ 'Bọ ti Iṣe ọjọ kedọgbọn oṣu yi.

ETO IPADE

Ẹniti yio ba wọn sọrọ ni Alagba G. D. Francis, ohunti yio si sọro le lori ni 'EDE YORUBA'

Ẹ jọwọ ẹ ma sai wa si ipade yi, a lero pe ẹ o tete de atipe ẹo si tun mu awọn ọrẹ nyin wa. IRE O!

OLADIPỌ YEMITAN

Akowe Ẹgbẹ


IWE KOṢEMANI NI EYI
IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo "YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO fun ara rẹ

"KOṢEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta Postage 9d tete lo ra tirẹ ko to tan

FI OWO RANṢẸ SI -
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue,
LAGOS NIGERIA
[illegible]

# IROHIN IMOLE

MOLẸ ỌRẸ AIYE ẸNI GBOGBO LAWA

No 1,565 MONDAY NOVEMBER 22, 1965 (2)


## Olori Ẹgbẹ Dẹmo Kan Pada Si Ẹgbẹ Afẹnifere

SHOMOLU Ni nkan bi ọsẹ mẹta sẹhin ni irohin ti de si ile iṣẹ wa ni jakejado ilẹ Naijiria ati paapa julọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun lori awọn Olori ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP ti nwọn binu fi ẹgbẹ na silẹ ti ọpọlọpọ wọn npada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre ati alakukọ lori eto abayọri idibo si ile Igbimọ Aṣo fin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to kọja lọ yi eyiti awọn enia Ipinlẹ na ndana sun ile ara wọn ti ọpọlọpọ ẹmi si ti ṣofo.

Ninu irohin to de ọwọ wa ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni ọkan ninu igi lẹhin ọgba ẹgbẹ Dẹmọ Imam Abudu Ṣeriki ti adugbo Pedro ni ilu Shomolu binu ku ro ninu ẹgbẹ Dẹmọ ti o si pada si ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilẹ Naijiria.

Ninu ọrọ Imam Abudu Seriki fun Oniwe Irohin wa ni o ti ṣe alaye pe on kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ ati pe on si pada si ẹgbẹ Afẹnifẹre ye it on nṣe tẹlẹ Imam Seriki tun ṣe alaye pe ninu egbe Afenifere ni on si ti wa tele ati pe lati igbati on ti wa ninu ẹgbe Demo o ni ọkan on ko kuro ninu egbe Afenifere.

Imam Abudul Seriki tun ṣe alaye pe lati igbati on ti wa ninu egbe Demọ ni ko tisi ifọkanbale kankan ati pe on ki yio tun wa ninu egbe ti awọn enia ipinle Iwo Orun ko fe lati ṣe eto akoso Ijọba le wọn lori,

# OJOORO WA NINU IBO IPINLẸ IWỌ ORUN

### Lati Oju Ewe Kini

a ni ile ifi owo pamo ti National Bank fun Ijoba ibilẹ ilu Ile-Ifẹ

Ọgbẹni Esua tun ṣe alaye pe awọn Akọwe eto ibo to kuro ninu ile iṣe wọn tabi awọn to salọ fi han pe nwọn ko fẹ ki awọn enia ti wọn ylo dibo fun yoku fi iwe ẹri idibo wọn silẹ ati pe lati le jẹki ẹgbẹ oṣelu ti o ti fi orukọ rẹ silẹ wọle laisi Alatako.



Alhaji D. S. Adegbenro Adele Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ọgbẹni Esua sọ pe gbogbo eleyi lọ si han si on lo ju nigbati on pẹlu Ọgbeni J, A Adegbitẹ ti iṣe Alako so eto ibo gẹgẹbi on jijo lo si awon ilu wonyi Ọwo, Ekiti, Ondo, Ado-Ekiti, ati Igbara-Odo eyiti o jẹ pe awon ko ba awọn Akowe eto ibo ninu ile iṣẹ won ti awon Akowe na si ti salo.

O ni Igbimo eto ibo tun ṣe ikilo lati ripe awon Igbimo eto ibo lati gbo telẹ ki ki nwon to ṣe ikedẹ pe awon enia kan wole laisi Alatako eyiti awon Akowe eto ibo na kuna lati jẹki awon Ibimo eto ibo gbo ki nwon to ṣe ikede pe enia kan wole lasi Alatako.

Ọgbẹni Esua sọ wipe awọn Akọwe eto ibo na ko tẹle eto ofin eto ibo ti apa kọkandinlogun (Section 19) Ori kini (1) (b) ti iṣe ti eto Ofin ibo ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ki o to di wipe nwọn nṣe ikede pe ọmọ ẹgbẹ Oṣelu kan wọle laisi Alatako ati pe eto ofin na sọ pe Igbimọ eto ibo ni lati gbọ wipe enia ko sọ wipe on ko dibo mọ tabi pe enia kan wọle laisi Alatako eyiti awọn Akọwe ilo na kọ tẹlẹ.

Ọgbẹni Esua tun ṣe alaye pe awon ẹniti o wọle laisi Alatako na ko ni gba iwe aṣẹ pe on wọle laisi Alatako ki nwọn to ṣe ikede tabi pe ki Igbimọ eto ibo iye awọn enia to ku lati dibo fun.

O ni eto Ofin ibo ti apa kẹrinla ori kẹta tun sọ wipe ọrọ ti akọwe eto ibo ba ti sọ wipe ẹnikan wọle ni yio jẹ otitọ ati pe ki yio si pe enia kan yio tun ma bere o ni on lo mu awọn Akọwe eto ibo na le ri aye salọ. O ni awọn Igbimọ eto ibo ko tun ni agbara lati yoju si ohunti awọ" Akọwe eto ibo nṣe.

O ni ohunti o tun jẹ aleebu ninu ibo na ni pe Akọwe Igbimo eto ibo Ipinlẹ Iwọ Orun ni o tun jẹ ẹniti o yan Awọn Akọwe eto ibo tabi pe ki nwọn yọ wọn kuro lẹnu iṣẹ na ati pe enia kan na ni Akọwe Igbimọ akoso iṣẹ fun Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria.



OLOYE AKINTỌLA
Olori Ẹgbẹ Dẹmọ

### IWE IBO

Ọgbẹni Esua tun ṣe alaye pe ki awon to ṣe idibo lo jẹ wipe awon ti nkegbe pe nwon enia kan ti lo tẹ iwe ti nwon yio fi dibo ati pe, O tun ṣe alaye pe lori eto nwon ti ṣe lori gẹgẹbi nwon yio ti tẹ awon iwe ti nwon yio fi dibo na eyiti Ọgbẹn Esua tun ṣe alaye on ko ni so nipa eto na ni sisiyi. Ọgbẹni Esua tun ṣe alaye pe ohunti ko tona lati ri pe enia kan tun lo ntẹ iwe ibo jade eyiti o lodi si ofin

## LATI OJU EWE KINI

Ogbẹni Andrew Ọtẹsile tun ṣe alaye pe ohunti o mu ki Ijọba ibilẹ ilu Ikẹnnẹ fẹ fi hu iwa ti nwọn nhu yi ni ọna bi nwoo yio ṣe tun le ri ọna wa ṣe iṣẹ ibi wọn eyiti o jẹ wipe nigbati gbogb ilu ba wa ninu okunkun awọn on ṣe ibi yio ri aye ma ṣe iṣẹ ibi wọn, eyiti yio tun fa nkan miran si arin na

Oniwe irohin wa tun fi ye wa ninu irohin rẹ pe gbogbo awọn enia ilu na pe epo Kẹrosini nwon fi ntan ina atupa Bakabula ati pe ọpọlọpọ lo jẹ wipe epo pupa ni nwọn nlo lati fi tan ina ti nwọn yio fi ma a miran to ba ti di alẹ.

Nigbati oniwe irohin wa lo si ile iṣẹ Ijoba ibilẹ ilu Ikẹnne ni o ti ṣe alaye pe on ko ri lati fi oro wa lenu wo atipe on ko tun ri Akowe ti Ijoba Ibile na lati wa di ohunti o fa ti ko fi si o m i ni ilu na ati pe ohunti o tun fa ti ko tun fi si ina monamona ni ilu na pelu.

Ṣugbọn Ọkan ninu oga agba ni ile iṣẹ Ijọba ibilẹ ilu Ikẹnnẹ tun ṣe alaye fun Oniwe irohin wa pe ohun ti o fa ti ko fi si ina mọnamọna ati omi ni ilu na ni ọda owo ti o da Ijọba ibilẹ na lo si fa eleyi wa ti ko fi si ina tabi omi fun awọn enia ilu na lati lo.


Printed & Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45 Campbell Street Lagos, 22/11/65